The Chief Secretary
to Government
Lagos

from P. A. Obasa
Editor & Proprietor
Yoruba News
Ojumpa Rd
Ibadan

# The Yoruba News.

**FOR GOD, THE KING AND THE PEOPLE.**

VOL. I. No. 23. IBADAN, TUESDAY, JUNE 17, 1924. Price 1d. Weekly


## S. AGBAJE & CO.,

*General Merchants.*

HEAD OFFICES:
GBAGI & AYEYE MARKET
Ibadan, Nigeria.

21 JUN 1924

Suppliers of:
**Palm Kernels, Palm Oil, Cocoa, Maize, Rubber, Ivory &c., &c.**
also
**MOTOR TRANSPORT SERVICE**
**Throughout the Western Provinces of Nigeria.**

CALL & SEE
## S. G. IROKO.
*HIGH CLASS TAILOR.*
At
Gbagi Street Iddo Gate,
Next Door to Messrs S. AGBAJE & Co.,
IBADAN.

*For Your*
MORNING DRESS, DINNER JACKET, LOUNGE SUIT, EVENING DRESS, Etc., Etc., Etc.
In the latest
London Fashion,
AT REASONABLE PRICES.

## L. L. RICKETTS
*AGRICULTURIST.*
YEMETU STREET,
P. O. Box. 136. IBADAN.

Expert advice on the Agricultural Resource of Yoruba Land will be given to Amateur Planters on Application:--

Instructions with regards to Soil, Planting, Planting Seasons and the general routine of cultivation.

Selected, Plants of Ghanja Kola are supplied on reasonable terms and various useful plants including fruit trees etc., etc., etc.

Also: Instructions on the preparation, handling and storage of produce. An interview will prove interesting.

Correspondence will be carefully attended to.

tracts confirm the fancies of the women public :—

LAGOS.

"Rain prevented the children's Sports at the Field taking place last Saturday Empire Day. But on Monday the 26th instant, the children had their feasts in their respective Schools in Lagos as usual and on Tuesday Sports were held."

ABẸOKUTA.

"Once again the Empire's children were assembled in memory of the great English Queen who built the British Empire x x The afternoon was given up to sports and the children thoroughly enjoyed themselves; having been feasted in their respective Schools before noon."

*The Nigerian Spectator, 31st May.*

"Empire Day Celebration, Ibadan, 1924.',

"The 24th of May this year was a Red Letter Day in the annals of this Province. Preparation for feasting the children was started on Friday. A fatted bullock was killed, prepared and cooked in readiness for the children who will attend the celebration next day x x x

Much praise is due to the District Officer Mr. R. H. Lapage, for the success of the Day, for he laboured throughout the day in every direction by . . . . supervising the feasting of school children on the race course." *The Yoruba News, 27th May.*

We have seen with pleasure, the efforts of Mr. A. Savage the Head School-master of the Government School in marching the boys to the Parade Field on the Empire Day; but we appeal to him in time before next celebration to lay the matter before the Director of Education Northern Provinces. The Southern and Northern Nigerias have been amalgamated and there is no reason why the Northern Schools should be exempted from Children's Feasting on Empire Day.

ARRIVALS.

Iya "Bọla" Adefọpẹ returned from her trip to Ibadan—Lagos on Saturday morning the 7th June-Barika dè sià—Ku àbọ.

TRANSFERS.

Mr. Laṣeyi arrived here with his wife on Saturday 7th June on transfer from Lagos to Audit Department. We welcome him to the North.

VISITORS.

Mr. Joseph Agusiọbọ of the Sanitary Department arrived here from Lagos to pick up his wife and children who were left when he was transferred to Lagos over 6 months ago. Sai wata rànà.

DEPARTURE.

The Lieutenant Governor with the Secretary J. S. Brown Esq. and their attendants left here on Friday 6th June on a trip to Zaria.

A FREQUENT CONVICT.

Mọmọ Ṣokoto, Alias, Langalanga arrived here last Thursday 5. 6. 24. from Zaria with Police escorts convicted to 6 months imprisonment for stealing.

A CLEVER ROGUE.

A young man Busu stole a fine table knife belonging to one Daniel Olu, a member of St. Maichael's Church Kaduna and resold it for 6d on Thursday the 5th June. He pleaded before the Cantonement on being tried next morning that he was moved by hunger to steal. The Cantonement mitigated his sentence by offering to engage him as a labourer, but the ungrateful rogue ran away without saying nà gòdè I thank you.

ARRIVALS.

Revd. W. O. Aiyedun B.A., arrived on Saturday morning the 11th June to take up duties as Pastor of St. Michael's Church Kaduna. Many of his members were in the Railway Station during the whole night. Unfortunately, the train came in so late at about 5. 35. a.m, that some of the bystanders who went to meet their friends expressed their desire in fun that if it were possible for them to build their own Railway, they will not allow Reverends to ride on it; it is becoming a real peculiarity that whenever a Reverend is in a train the same must run late.

The expression was endorsed by others through their past experience in case of Reverend Ajibọla's arrivals after his ordinations as a Deacon and Priest respectively. However the train did arrive and the Reverend gentleman was conveyed to the Parsonage in a horse drawn Go-Cart, accompanied by his warden

We heartily welcome him to the North and wish him a very happy time among his Congregation.

FOR SALE.

**REO LORRY**

**No. 00.263.**

In good running order.

*For full particulars please apply to*

THE EDITOR, YORUBA NEWS, BOX 60 IBADAN.

# "AWỌN AKEWI"

OR

# YORUBA PHILOSOPHY.

## ẸRU.

Tani i sọ ọmọ rẹ l' Ẹru ?
A f'ẹni Ọtẹ tẹ, a f'ẹni ogun mu,
Ni i d' a mu f' owo ra,
Oun ni i j' Ẹru.
Ẹru ku ninu ile,
A ru 'ku rẹ r' oko,
Ọmọ si ku l' oko,
A ru 'ku rẹ wa 'le,
Bibi wọn ko tilẹ ju bibi lọ,
Bi a ti b' ẹru,
Bẹ nā l' a bi ọmọ ;
Ika enia ni i wipe :—
T' ẹru n' ipa, t' ọmọ n' ibi
Oyun ẹru ni i d' ẹjọ,
Ija rẹ nā ni i tu 'le.
Ẹru ni i r' oko lāriọ ẹgun
Ọmọ olowo ni i ro
Ni gbangbà oko.
T' ẹru n' iṣẹ, t' ẹru niya,
Ẹnyin ẹlẹru
Ẹ má ṣika mọ.
Ọlọmọ ki i sọ ọ l' ẹru,
Ọtẹ ni i sọ oju ọmọluwabi
Di ti ẹranko.
Ọtẹ muyiwa,
Ogunbilejẹ, Ogunrunbi,
Ọba Dàdá
Ẹru Ọba Kùrukùru !
A ti kekere ṣ' ẹru,
Ko mọ 'yi Ọtẹ.
Ẹni-ọtẹ nki ara rẹ, o ni
Oun Okoro-mb'-ogun-jẹ
Njẹ o ti ṣe o t ɔ d' ẹru ?

Iwọ Okoro-mb' ogun-jẹ.
B' ẹru ba pẹ n' ile
A nā ba wọn bu " Ajọbi "
Oju to 'le, oju t' oko :
Ẹru t' o l' oun o ṣu'po ;
A bi sọ si Gàá,
Nwọn ko mọyi olowo :—
O d' ijọ a ba r' ogun !
Olowo wọn a ni " Ojo
Yara m' ẹru mẹfa ni Gàá,
Rè i fi nwọn k' Ẹtu l' Ajaṣẹ
Ng ri 'untmu r' ogun,
Si mu mefa o r' Ọna-Jẹbu
O fi nwọn ra Aṣadi-ibọn.
Ẹta-Elege mbẹ tab' o buṣe ?
Ahaya mbẹ tabi ko si ?
Aṣọ Ododó sunwọn l' Amure :—
Bi Gende ba ta mọra l' oju ogun !
B' aṣọ Ododó ko ba to,
Yara sare r'ọja o ra si i—
K' o le kari ọmọ-ogun."
Ojo dahun, o ni " Baba,
At' Ahaya at' Amure Ododó
T' o ku n' le ko le kari,
O di bi a ba r' ẹru wẹwẹ
Nina ọmọ Olọko-ẹṣin."
" Ojo o ! mo ni o tun lọ si Gàá
O re i pe nwọn wa—
Awọn ẹru-kẹru, a bi Lala l'ẹnu ;
O mu meji wọnyi
O re i ta nwọn 'nmi 'a,
Ka r' ohun di'ra ogun.
Bi a ba ja l' ajaṣẹgun
Bi a ba m' ójó l' Ẹru,
Akọni nwọn di pipa.
Kokoyi m' Oibo goke !
Ogun tan patapata,
Ẹru ko si mọ ;
Gbogbo Ẹru d' ọmọ.
Tani nlọ mbẹun ? Ko si mọ,
Gbogbo wa d' ọmọ Ọba !

# IṢE OLODUMARE DISPENSARY.

Joshua O. Ade: Craig,
*Manager & Proprietor,*
Established 1918.



LAGOS.
116 Great Bridge Street,

IBADAN.
Iddo Gate.

## KINI ṢE TI O FI RU BAYI?

Ikọ nwu ọ ni?
Ori nfọ ọ ni?
Inu nrun ọ ni?
Akokoro nba ọ ja ni
Otutu nmu ọ ni?

Mā bọ ni ile Egbogi ti a npe ni "IṢE OLODUMARE."

Ẹsẹ ndun ọ ni?
Eti ndun ọ ni?
Ehin ndun ọ ni
Oyi nkọ ọ ni?

Mā bọ ni ile Egbogi ti a npe ni "IṢE OLODUMARE."

Iwọ ko ri Igbọnsẹ ṣe?
Iwọ nṣe Igbọnsẹ pupọ ni
Oju ndun ọ ni?
Iwọ ko riran kawe ni?

Mā bọ ni ile Egbogi ti a npe ni "IṢE OLODUMARE."

Nkan-ki-nkan ti o wu ko ṣe ọ mā bọ ni Ile Egbogi yi, ni Gbagi odojukọ ile ọja Oyinbo Ajẹ (G. B. OLLIVANT). Ile Egbogi na ṣi silẹ lọsan ati loru, bi ọfẹ ni gbogbo rẹ, fi oju kan Alabojuto ibẹ yio tẹ ọ lọrun, iregbe ni yoku "Arûn ma jogûn, ndagba si Ẹlẹda re."


Printed and Published by D. A. OBASA at The Ilare Press, Ogunpa Road, Ibadan.

# Ẹ MA ṢỌ O!
# KI NU U?
## OJO PATAKI
TI
# OIBO ALAGBON

(Ile Owo Ekini ni ile yi

yio ṣi Ile-Ọja Titun ti nwọn ṣẹṣẹ kọ si

BODE IDO, IBADAN.

Orişirişi Aşọ, Işọşọ Wòsìwósì, Awo Abọmafọ, Ohun-Elo onirin oniruru ati Ọpọ Orişi Ọja miran lo mbẹ nibẹ.

Ẹ MÃ ṢARAJỌ!!

**Ibadan Billiard Saloon.**

Ido Gate, Gbagi, Ibadan.
Opposite P. Z. & co.,
GAMES:
Billiard, Skittles, Dominoes, Draught, Ludo, Cards and Sprian Draught also Dancing
EXCELLENT MUSIC PROVIDED.

A Bar is attached for the convenience of visitors.

*M. K. Assaf,*
Manager Commission & Agent.

# TO LET.

D. W. OKUṢỌTẸ,

*Tailor & Draper.*
Gbagi Street, P. O. Box 160, Ibadan.

All kinds of Gentlemen's Garments accurately built in the latest style
Satisfaction Guaranteed.
Charges Moderate.
ALSO
Dealer in Machine & Cycle parts.
Gents' & Ladies' Headwear

Cheap! Cheap!!

PLEASE GIVE A TRIAL.

# HUDSON COLE,
*Builder and Contractor.*

*Undertakes & executes all kind of*
*BUILDINGS &*
*OTHER CONTRACTS*
*in any part of Nigeria*
*Plans & Estimates prepared.*

Lagos Address:
40,A. JOSEPH STREET.
Ibadan Address:
GBAGI STREET IDDO GATE.

# OWUYẸ.

## SOBIYA.

Sobiya nyọ ilu lẹnu nisisiyi. Ko si ile kan ni arin igboro ti a ko mba arun yi pade. T'ọmọde t'agba t'ọkunrin t'obinrin "Awopọ ni Gbodogi nwo'mu."

Ko tilẹ ṣẹ rara ni ni gbogbo abuleko. Ni Aba Balogun ni Ọna-Alawọ, ko daju pe enia mẹwa kù nibẹ ti sobiya ko da; bẹnã ni lọ titi de ẹsẹ Oke Ibadan; gbogbo iṣẹ awọn Agbẹ wọnyi lo duro patapata nipasẹ sobiya.

Omi ti ko dara ni nmu sobiya wa. A mbẹ ẹnyin Baba wa Ajẹlẹ, Balẹ ati Igbimọ lati ba ni tọju omi ti o dara ni mimu fun lilo ilu ati igberiko gbogbo.

---

Mọto ṣe iya kan ni ijamba ni Agodi nipa yiya sihin sọhun ni ọsan ijeje.

---

Mọto A221 wu ọmọkekere kan lewu ni ọkankan Ile Ogbẹni J. M. Ọdunsi ni iwọn agogo meji ọsan *Wednesday June 11.* A dupẹ pe Popọla Awa-Mọto yi nlọ ni iwọn ti ofin wi, bi koṣe bẹ, i ba soro fun u lati le ko Mọto nã ni ijanu laseko. Mọto i ba si pa ọmọ nã patapata.

---

A gburo pe awọn kan pin iwe kekeke ni Ejigbo fun awọn bãle–bãle ni oruko Elejigbo, pe, ki olukuluku bãle wọnyi san £3, pọnun mẹta mẹta fun igan pãnu ile kọkan ati sile mẹfa mẹfa owo ãru rẹ fun Ile Elejigbo tabi ile-Ọba. Lẹhin ọjọ melo kan si i ni nwọn tun lu agogo ọrọ kannã yi.

Amu da gbogbo Ejigbo nitori ọrọ yi. Igbe "Emi nla, ki l' a ri yi?" Ki a jaya owo ojule k' a si tun jaya owo pãnu Ile Oba" gba gbogbo ilu kan. Ọrọ yi ko ye ni rara, nitoripe Baba L' Afin fi Pãnu kọ gbogbo Afin lai gba kọbọ lọwọ ẹnikẹni, Ṣitu Bãlẹ Ibadan kọ ile pẹtẹsi nlanla meji lai gba owo lọwọ ẹnikẹni. Ẹyi ti jẹ? Ewo ni ti Iwe kẹkẹkẹ ti ko **ni orukọ ẹniti o kọ nwọn ti a pin** wọn kiri fun gbogbo bãle-bãle Ejigbo? Ṣugbọn a ko ti i gba ọrọ yi si otito. A nwa idi rẹ lọwọ.

---

## AJINDE OKU TABI IPARADA ???

Ni Sunday June 9 ọmọkunrin ti njẹ Amọdu ni oko Ẹgàn niwaju Onipẹ sọ fun awọn obi rẹ pe inu kan nrun oun. Nwọn pe gbogbo onisegun arọko nã lati wa wo o ṣugbọn ko san fun u o ṣa ku dandan ni awurọ ijọ keji.

Ohun ti o jẹ iyanu ni pe nigbati o di ọsan ọjọ kẹrin Thursday June 12 ni aburo baba ọmọkunrin ti o ti ku yi, obirin ni ile Arẹ-Onibọn l'Oke Mapo ri Amọdu ti o wọle wa, o kuulẹ o ki aburo baba rẹ gẹgẹbi awọn ọkunrin imale ti i mã kunlẹ ki enia, nwọn si ki ara wọn. Amọdu, dahun o ni oun ko ba Olorukọ-ọba (Ṣitu) ni ile ? Nwọn ni ko si n'ile.

Amọdu dahun o ni oun fẹ lati mu ṣokoto ati akẹtẹ Panama ti Olorukọ-ọba ti o fi kọ si ori-ikọ (Rack) ni inu ile, nitoripe nwọn nfẹ fa Iyawo oun wa fun oun ni oko wọn l'Onipẹ lọhun.

Iya Olorukọ-ọba ni ki Amọdu mã mu ṣokoto lọ, o gba a silẹ lọwọ rẹ, o jẹ ki o mu akẹtẹ (Panama) nikan lọ. Iya nã sọ fun Amọdu pe ki o ranṣẹ wa gba gbogbo ohun ti o ba nfẹ lọwọ Olorukọ–ọba l'ọla. Nwọn ni ki o duro ki o jẹun ki o to mã lọ, ṣugbọn o kọ, o ni awọn Ẹgbẹ oun ti awọn jọ nlọ si oko duro de oun ni Ọja'ba ati pe oun fẹ de ọdọ Esuru ẹgbọn Olõkọ-ọba ni ile ọkọ rẹ ni Alekuṣọ. Ng ni Amọdu ba jade lọ.

Nigbati Olorukọ–ọba ti ibi-iṣẹ de ni iya rẹ jiṣẹ fun u pe Amọdu wa ile, o mu ṣokoto ati Panama ṣugbọn oun gba ṣokoto silẹ, o mu Panama lọ. Olorukọ-ọba dahun o ni "Kini ṣe ti iya oun ko da Amọdu duro de oun ? Ṣe oun iba mu aṣọ daradara fun u ni inu apoti ?"

Ni agogo mẹfa ku iṣẹju mẹdogun ti alẹ ọjọ ni Esuru pẹlu obinrin meji wa tu ọfọ pe Amọdu ku l'oko ni ijẹrin. A fi Ha ! Ha ! ! Ki l' a ri yio ! ! !

## OṢOGBO June 6.

Ọgbẹni Ailayọ, Ọga Akọda Oṣogbo ṣe laisi ni iwọn agogo mẹrin irọlẹ June a 6. Ologbe yi ni Ijọba gba si inu iṣẹ Akọda lẹhin ti o ti pari ọdun pupọ ninu iṣẹ Ṣọja, o si fi gbogbo ara ṣe iṣẹ titi ọjọ iku rẹ. A ṣe idaro awọn ẹbi, aya ati ọmọloku. Ẹ ku ọfọ.

---

## IROHIN IGBEYAWO.

Ni ọjọ karun oṣu yi ni Ọgbẹni James Ajani ṣe bẹbẹ ni Ogbomọṣọ. Ọgbẹni yi jẹ ọkan ninu awọn olukọni wa ti o ti jade ni Ile Iwe Giga ti o wa ni Ogbomọṣọ, o si nṣe iṣẹ olukọ ni Ẹdẹ.

Agogo mẹjọ ni Ọgbẹni na ati Alufa ti yio ba wọn ṣe igbeyawo pinnu lati de *Church* Oke Lerin nibiti nwọn yio ṣe Isin Igbeyawo yi. Ṣugbọn kutukutu awurọ ọjọ *Thursday* ti iṣe ọjọ igbeyawo ti a wi yi, ojo rọ pupọ tobẹ ti a ko fi le lọ si Ṣọsi titi o fi di bi agogo mẹsan kọja iwọn iṣẹju mẹwa.

Nigbati Ọkọ-iyawo ati Iyawo ti ṣetan olukuluku enia ni ile rẹ, Alufa lọ fi kẹkẹ rẹ (Ford) gbe Ọkọ-iyawo ati Iyawo lọ si *Church*, Papin ni !! Mo gba fun wọn pupọ.

Gbogbo awọn ti o wa ni ibi iyawo yi mọ wipe igi da nitotọ ! A ko gbọdọ tun sọ si ti aṣọ ti Ọkọ-iyawo ati Iyawo nā wọ mọ, o tayọ ohun ti a ba tun mā f' ẹnu sọ. Bi o ba ri aṣọ ogbọ iyebiye ti iyawo na wọ, o dabi ẹni pe a bi i mọ aṣọ na ni.

Nigbati nwọn ti de Ṣọsi, nwọn ni lati duro diẹ fun awọn ọrẹ pupọ ti ojo ti di lọwọ lati de ni akoko. Ko pẹ lẹhin igbati Alufa Ẹni-ọwọ W. H. Carson ati awọn olukọni de, ni a ri (*Organist*) Aluduru nā to de. Lẹhin nā isin bẹrẹ pẹlu orin. Si ma wa wo ọwọ ọkunrin nā lori ẹrọ-ikọrin yi ; ko lẹgbẹ! O dabi ẹnipe ọwọ Aluduru na ati Duru yi ni Ṣọsi ra pọ lati Ilu Ọba. O ku 'ṣẹ o, Olorin!!

Lẹhin igbati Alufa pari isin ti o si pe Ọgbẹni James Ajani ati Iyafin rẹ ni ọkọ ati aya, awọn enia bọ sode. Bi Ọkọ–iyawo ati Iyawo rẹ ti bọ s' ode, ti wọn si duro diẹ ni awọn onilu, awọn aluṣẹkẹrẹ, ati awọn aludundun de. Awọn onilu wọnyi ṣiṣẹ pupọ. Nigbati ilu bẹrẹ si iro ni awọn enia wa nwọ bi omi tẹle Ọkọ-iyawo ati Iyawo lọ si ile Iya-iyawo. Wa wo bi owo ti npe owo ranṣẹ bi wọn ti nlọ. Inawo na pọ pupọ. Awọn obinrin ko mọ pe akoko nsare mọ, nṣe ni wọn ntabiran ti nwọn si njo bi arokoto. Tobẹ ti o fi di agogo kan kọja iṣẹju mejila ki a to pada de ile Ọkọ-Iyawo. Onjẹ bẹrẹ lori tabili ni agogo kan-abọ

Onjẹ wa npe onjẹ ranṣẹ ; Ṣibi nkọlu ara wọn ; agunjẹ ati ọbẹ nmōkun ninu ọbẹ̀ ; ōruñ alubọsa ati ero'ja ọbẹ̀ iyoku ko fẹ ka tun ma to wọn woro-wẹrẹ mọ. Ah ! ọmọ enia jẹ pẹrẹ onjẹ danu sibẹ. Bi a si ti ro wipe a jẹun tan ni irẹsi tun de pẹlu omi-ọbẹ̀ ti nta firi lori rẹ. Sa ma wa wo bi ā ti i jẹun.

Lẹhin onjẹ ni *Chairman*, (*organist* ti mo ti m' ẹnu ba lẹkan) wa npe awọn ti o ti yan l' ọkọkan lati sọrọ. Gbogbo ọrọ ti olukuluku wọn sọ li o kun fun ọgbọn ati ironu. Ọgbẹni ti o sọrọ kẹhin ni Oniwasu Ijọ Baptist Ijẹru Ọgbẹni na si sọ kutupu ọrọ nipa Omidan ti a gbe n'iyawo yi ; nitoripe ọkan ninu awọn ọmọbinrin Ṣọsi rẹ ni iṣe. Ọgbẹni Ajani ati Iyawo rẹ, Ẹ ku inawo ki Oluwa ki o fun nyin ni alafia ni ile nyin o Amin.

---

## ILEṢA.

A ki Ọgbẹni Albert Jẹgẹdẹ ku ọfọ Iya rẹ t'o ku ni *June* 1. Oluwa ko f' ọrun kẹ ẹ.

Ẹni-ọwọ Ṣodipẹ, B.A., fi otitọ ọrọ han awọn ara Ijọ Ọmọfẹ ni Ileṣa nigbati o lọ wasu fun wọn ni *June* 1 lati inu Lefitiku 11: 14.

A yọ fun Ijọ Ileṣa nipa ọmọ Ijẹṣa kan ti o gba oye Alufa. Ẹni-ọwọ Adedeji, oye a mọri o.

---

Ki Oluwa, gba ni lọwọ awọn Ọlọṣa arunlẹ kole. Ni oru Friday mọju

Satide 7. 6. 24. ni awọn Ọlọsa gbẹ Iganna Ọgbẹni Ilesanmi ti wọn ko ẹru Ile-ọja rẹ lọ. Oluwa ko fi ofo ra ẹmi o Ara miran l' ode, ole ki i ja ni Ilẹsa. A ro pe awọn Agbàgbà yio ri si ọrọ yi, lati fi enia si ode ṣiṣọ loru.

---

Atun gbọ pe awọn Ọlọsa kole ọkunrin ti a npe ni Omirin ni Ọsogbo ni ọjọ Ọsẹ 8. 6. 24. Ile-ọja yi ki iṣe ti ọkunrin yi; o gba ọja lati ọwọ awọn Oibo Ajẹ, G. B. Ollivant ni. Oluwa yio tu Aṣiri awọn ole yi.

---

Ọmọ-ọba George Adetọna Haastrup Ajimọkọ sin ọmọ rẹ niyawo fun Ọgbẹni Alawo, Oniṣẹ awọn Oibo P.W.D. ni Ọjọ Isimi 8. 6. 24.

Oluwa ko fi ọmọ kẹ wọn Amin. Baba ọmọ nawo pupọ; bayi, bayi ni ki a mà ri o.

---

## IROHIN LATI EJIGBO.

"Bi alejo ba ju onile lọ, Ibosi lã ke."

Bi ọrọ kekere ti a sọ loke Iwè yi, bẹni o ri nigbati awọn ọmọ Balogun Oguntunde, daṣa lati ke si Ọba Elejigbo pe, ko wa ba awọn si Ile wọn.

Nigbati o di oju ọgbọnjọ oṣu May, 1924 eyi ti i ṣe ọjọ Jimọ ti o dapọ mọ Jakuta ti gbogbo Imọle ati Yōba yaṣọtọ bi ọjọ kan pataki ninu gbogbo ọjọ, (ti itumọ rẹ ko ye awa Onigbagbọ tobẽ-bi Ṣango ni nwọn nfi ọjọ nã yẹsi ni o, a ko mọ.) Nwọn npe e ni Jimọ-oloyin

Nitoripe, l' ọjọ Jakuta ijọkandilọgbọn ni Elejigbo pāpa si ile tirẹ fun awọn ọmọ rẹ. Ni ọjọ yi gãn ni awọn enia wọnyi ti mura silẹ de gbogbo awọn ti yio wa. Bi ilẹ ọjọ nã ti mọ, bẹni awọn enia yi ti bẹrẹ si i mã na owo; nwọn si wa ninu iyemeji pe tabi Elejigbo yio wa, tabi ko ni wa, tabi ko ni wa mọ!

Bi o ti to agògo meji ọsan, bẹni ariwo Ilu, Bata, Ṣẹkẹrẹ, Kósó ati Fere sọ, ki awọn onile ko bọju wo ode, ṣiṣú ni Ẹṣin ati enia ṣú dẹdẹ bi ojo tobẽ ti gbogbo onile ati awọn aladugbo dãmu, bi ile na ti tobi to ko gba enia. Ohun to ya ni lẹnu ni wipe Lemọmu ati awọn enia rẹ to pẹ diẹ lẹhin, ni iti ni nwọn gbe joko si.

Bi enia ti pọ to yi ko si ẹnikan ti ko jẹun ajẹti. Akukọ adiẹ ju Ọgọji lọ ti awọn aladugbo nfi ṣe alejo. Agbọn nla kan ti nwọn nda Obi si, si kun. Nigbati awọn onile pāpa yio ṣe lapari alejo, agbọn nla kan ni nwọn fi ko Igo Ọti Oibo si; nigbati enia Elejigbo yio ma ko Ọti yi kuro ninu agbọn, nwọn ba Ọkẹ mẹwa (£2-10-0) ni alẹ agbọn nã tobẹ ti Elejigbo pāpa fi kọ "Ha!" Lẹhin jijẹ, ati mimu, ni Elejigbo bẹrẹ si ijo yi ile nã po. Lẹhin nã o si sure fun awọn ọmọ nã o si sọrọ iwuri, bi baba awọn ọmọ nã ti dābobo oun, nigbati bàbà oun ku tan ti "Ina-Ọla" si fẹju si oun.

A bẹ gbogbo ẹnyin akawẹ THE YORUBA NEWS, ki ẹ ranti ọba wa ninu adũa nyin, nitoripe asiki nã pọ, gẹgẹbi a ti mọ pe orukọ mẹta wọnyi fara-pẹra wọn, Asiki, Aṣitẹ, A o sinku.

Ki Oluwa ko maṣe jẹ ki a ri ẹtẹ ile aiye yi o.

---

### BOY SCOUTS.

**The 1st Ọyọ [Ibadan Grammar School] Troop of "B. P." Boy Scouts will give a Dramatic Entertainment entitled 'Joseph and His Brethren' at Ọja'ba Court Hall, on Friday the 20th inst at 8 p.m Captain the Hon. W. A. Ross, C.M.G., the Senior Resident will occupy the Chair.**

---

We regret to announce the death of Mr. Edwin Matthew at Isalẹ Oje Street, Ibadan The man was the Elder of the Church of God at Oje for over four years. He passed from tribulation of this world to the joy of heaven about 2. 30 p.m. on the 14th inst.

Mr. Taylor arrived from Lagos by Motor Car for the burial at 6. 45 p.m. on Saturday 14th.

We tender our sympathy to his widow relatives, and Co-workers Mr. Taylor of Lagos, Mr. Wallace and Miss. Mc. Fairley of Ibadan.

**THE YORUBA NEWS.**

*Editor & Proprietor:—*

D. A. ỌBASA,

*Office*:-AJABA SQUARE, OGUNPA ROAD, P. O. BOX 60, IBADAN.

*Subscriptions payable in Advance.*

Ibadan 12s, per annum. 13s Post Free in Nigeria 14s. Abroad.

Cheques and Orders should be crossed and forwarded to the Editor.

Advertising rates &c. application.

## OUR REPRESENTATIVE.

### The Honourable E. H. OKE.

THE ỌYỌ Province is rather fortunate in the appointment of its Representative to the Legislative Coucil of Nigeria. The choice of Elder E. H. OKE is one of the best that has yet been made to that august assembly. It will be received with universal approbation among every class of the intelligent community in the Province, and the whole of Nigeria. Given an equal opportunity of the Franchise like at Lagos and Calabar, the result of polling in this Province would not have proved otherwise-where age, experience, and knowledge of the country's needs are concerned.

Elder E. H. OKE is one of those Yoruba patriots who have served the interests of their country faithfully in many ways both by precepts and examples. Born in the town of Ijaiye when Kurunmi the Great Yoruba Generalissmo was in his glory. He was introduced to the Missionaries by his uncle Mr. S. Robert—a Repartriate from Sierra Leone —in the year 1860 after his father's death during Ijaiye Wars.

He received his early training from the German Missionary Rev. A. Mann and he subsequently entered into the Missionary Training Institution in 1868; together with Bishop Oluwọle and others, received their appointments as Tutors in the same School in 1872 where he remained for 14 years a Tutor.

He resigned the C.M.S. work and joined the service of the Government of Lagos in 1886, where, he held various appointments as Clerk, Store Keeper, Harbour Department, Chief Steward on board H. M. S. *Gertrude* from which position he was latterly transferred to the Prison Department as Chief Warder. He had acted on many occasions as Keeper of Prisons and for the faithful discharge of which duties he received pecuniary rewards from the Government. In recognition of his sterling qualities and worth, he was finally sent by the Government to England to study Prison Laws and Discipline in 1892. He studied in Islington and Kessington Prisons Pentonvilly and Wormwood-Scrubs. He resigned in 1907 after a record of excellent service to the government, covering 20 years.

He was invited to Ibadan to take up the newly established Bale's School, Ọranyan, from here he was offered the post of Secretary to the Ibadan Native Government which office he held from 1912 to 1916 when he resigned.

The part he took in the organisation of the U.N.A. Church is well-known—he is one of the few surviving originators of that body to-day. The Jehovah-Nissi Church at Idi-Ikan and the U. N. A. Church at Ijaiye are practical testimonies of his zeal for the advancement of Christianity in his country. In his capacity as an Elder of his church, he has laboured much for the benefit of Ibadan, by giving them sound advices and useful Lectures from time to time.

We congratulate the Senior Resident of the Province and our Baba L'Afin for the wise selection of our Representative to the Legislative Council of Nigeria.

## Iparoko.

Si Atẹwe Irohin "Yoruba News"

Alagba

Mo fi iwe gánngàn yi dupẹ lọwọ rẹ fun ọrọ àṣàrò nipa Iyawo Aredè ti o ba ni fi sode ninu iwe Irohin ti *June* 3. Oju ko ni ti ọ, ō fi iṣẹ nā le ọmọ lọwọ o, o ṣeun.

Jọwọ, ẹ̀bẹ̀ kan l'oku ti mo fẹ bẹ ọ, ojutaiye ni ẹnyin sa wà, ikọ̀kọ̀ aiye ni a wa nihin; ti o ba gbọ finfin pe nwọn tun fẹ ṣe Ajọdun Ẹgbẹ awọn Obinrin, ki o jọwọ sin mi ni gbẹrẹ eti, ki a le bẹ ọkan ninu awọn Iya wa Mrs Jemimah Oyebọde, Aya Baba wa, Ẹni-ọ̀wọ̀ R. S. Oyebọde ti Ilẹṣa, obinrin tōtọ, on ni o le ba wa tẹ ọrọ na mọ awọn ọdọ mọbinrin leti, nitoripe, "ẹniti yio bun ni ni ẹwù, t' ọrun rẹ̀ l'a wo" ōwe na ti ẹnyin agba o. O jẹ alagbara Obinrin (*very industrious.*) ko r' āye a nwe gèlè si gbègbèrẹ́jú kiri ile: ka ma reti igbàti "Adeọla yio ti odò de k' o to wa gba 'lẹ ile. Ọrọ na yio dun l'ẹnu rẹ̀ lati sọ.

Mo si tun dupẹ ōre ti o nfi Iwe Irohin rẹ yi ṣe fun ilẹ wa. Ajinde a jẹ o.

Emi ni tirẹ nitotọ,

Otitọkorò.

---

## IROHIN EKITI.

Pānu ti gori apakan Ile Ẹwi ni Ado. Ọna ọkankan ti o wọ inu Ile na si dara pupọ, pāpā gbàngàn ti a fi okuta se *Hall* eyiti awọn enia, ati Ijoye, ati Ọba le mā pade fun apero.

A ki Ọgbẹni Robert Ajẹlẹ kekere ti a ṣẹṣẹ mu wa si Ado ninu oṣu yi pe o kabọ; a si tun nreti Ọgbẹni Norcott ati aya rẹ ni Ado Ekiti laipẹ. Obinrin rẹ yi jẹ jámújámú ninu obinrin, ẹniti o ba ri i lori Mọto-Basikulu lo le mọ riri rẹ.

Ile Isin ti Ijọ C.M.S. di mẹrin ni Ikẹrẹ nisisiyi, nwọn si nmura lati bo mẹta ni pānu ninu ọdun yi. Nwọn ti bo ọkan, iṣẹ meji yoku si nlọ dōde; a ki Ọgbẹni J. Ale, G. Lagunju ati Gbadamọsi awọn Kafinnta atàtà, ku iṣẹ o.

"Ile Ọba to jo, esu ẹwà ni nbi i" Mọto Resident ni Akurẹ (Ford Pleasure Car) kan ti o jona ni Station Osogbo tun ji dide; o kuro ni ti anfani, nwọn sọ ọ di ti ẹlẹrù, dajudaju yio si wa wulo fun wọn ju ti atẹhin wa lọ.

Ọgbẹni Sam Ajayi (Road Overseer) ni Igbara-oke nsare gb'oke gb'odo lati igbati ojo ọdun ti bẹrẹ, nitori iru wahala ti nwọn ri ni ọdun ti o kọja.

Ọgbẹni P. F. Herbert (Inspector of Schools) Oludanwo ti Ijọba mbẹ ni Ekiti nisisiyi; o ti ndan awọn Ile-ẹkọ Ekiti wo. O bẹrẹ ni Emmanuel School Ado, awọn ọmọ ibẹ gbiyanju, mẹta ninu wọn (pass Standard V.) Lẹhin na o wa si St. Luke's School Ikẹrẹ, awọn mejeji ti o wa ni Standard five, Samuel Ayẹni, Fabikun, ati Solomon Ojo Adekanmbi *pass* pẹlu. Ọjọ keji o lọ si St. Mark's Ile-ẹkọ ibẹ, o dun wa pe awọn ọmọ Ile-ẹkọ ibẹ ko se dada. O wa ni apa Ifaki, Ijero, Usi, ati Aiyede nisisiyi.

Ẹsẹ kan nyọ ọ lẹnu lati Isẹ, ṣugbọn o nfi gari gbigbona ko o loju, o si nfuyẹ dādā nisisiyi.

Iye awa ọmọ Ibilẹ Ibadan ti a wa ni Ekiti a fi tọkantọkan ki Ijọ Baptist ni Idikan nipa ti ọfọ nla ti o ṣẹ niti iku Ọgbẹni C. L. Ọdẹbiyi a ko le gbagbe rẹ nigbati ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ Ile-ẹkọ Ekiti ba nkọ "Lor' agbelebu kalfari" ti a gbọ lati ẹnu olōgbè yi ti a si kọ awọn ọmọ Ile-ẹkọ Ekiti. Gẹgẹbi Egbe orin na "K' Oluwa ranti gbagbo wa o."

**ORIN ARO.**

Titi ao pade ni 'Salu ọrun,
T'a o gbọ ohun orin didun rẹ
T' a o jọ kọ, ki iṣe ninu ara.
Sun re, Sun re, Sun re.

## The Late Rev. M. N. Q. Sagoe.

From our Lagos Correspondent.

Rather sad indeed for yesterday's occurrence in the shocking news that awoke us in the morning of the premature death of the Rev. Michael Nun Quashie Sagoe, an able young and powerful preacher of the Wesleyan Church. His losswas greatly feit among his comrades and the general community—Oh! very jovial, always smiling and chatty.

He was only just transferred from Jẹbu District to Lagos District, Ereko Church—and one could judge how he was loved by the community of Lagos, by the great crowd of mourners following his remains to Ikoyi Cemetery for interment. He was of Masonic, Templa 's and Shepherd's Fraternities. The members of the latter formed in procession with the Choristers together with the following Ministers e.g:-Rev. H. W. Stacey (European) Principal of the Wesleyan Boys' High School, Rev. A. N. Cole, Superintendent of Tinubu Circuit, Rev. Evan E. Williams, Superintendent of Olowogbowo Circuit, Rev. S. A. Pearse of Ọbun Eko Church and Rev. D. A. Bababunmi of Williams' Memorial Ebute-mẹta Church; Wesleyan Boys' Scout and full representatives of Women's Associations also Fantee Church representatives were also part of the procession.

The Hearse which was used for the first time being belonging to Ereko Church "Ẹgbẹ Ifẹ" and which was clearly engraved upon the Glass of the Hearse: the procession was grand. They sang all the way to the Cemetery. After the conclusion of the service at the grave, the Women's Association sang "Sleep on Beloved" in a thrilling voice and the song was so pathetic and touching that a good many people were shedding tears.

He died like a faithful Christian. His last words to a friend who visited him on sick bed just before his passing away were "Rest in Peace."

## EKITI

### IPẸWO TI LIEUT. GOVERNOR NI AKURẸ.

Kio to to akoko ti Lieut Gorernor *Southern Provinces* de si Akurẹ, Ajẹlẹ kekere ni Ado ti kọwe si awọn diẹ ninu Ọba Ekiti lati wa pade rẹ ni Akurẹ. Awọn Ọba ti o si pejọ ni Akurẹ ni ọjọ *Wednesday May* 21 ni iwọnyi:-

1. Ẹlẹkọle (Olọri Alade) lati Ikọle
2. Ajero lati Ijero
3. Deji ni Akurẹ
4. Alāye lati Ẹfọn
5. Olojido lati Ido
6. Ogoga lati Ikẹrẹ

Ẹwi lati ado ran igbakeji rẹ Ọdọfin wa. Lieut. Governor papa de si Akurẹ ni ọjọ *Tuesday May* 20. Oun ati akọwe rẹ.

Ni ārọ *Wednesday* yi, ki o to to akoko ti Lieut. Governor de sinu Ile Kotu ni Ajẹlẹ kekere Ọgbẹni Clegg "A dara bi ọmọ ẹiyẹle" ti wa wo ohun gbogbo ati lati ṣe eto nkan gbogbo ki ọga rẹ adele *Resident* Mr. G. H. Findlay "gbogbo iṣe kiki fāri" ati Lieut Gov. papa to de, Lai fa a gun lọ titi Lieut Gov, pẹlu adele *Resident* de. Nwọn si ki awọn Ọba ti o wa; awọn mẹtẹta si joko Lieut Gov, si bẹrẹ si iba wọn sọrọ, Mr. S. Ade Ojo "oponu Ibadan" ti o nṣe akọwe *Resident* ni Akurẹ si ngbufọ fun u pe, Inu oun dun pupọ lati ri awọn Ọba ti o wa pade oun ni Akurẹ yi, ati pe Mọto ni gbogbo nwọn wọ wa: eyi fihan pe iṣẹ ọna nlọ dēde. O sọ wipe nwọn ko le ṣe eyi ni nkan bi ọdun marun sẹhin. O tun sọ fun wọn pe inu oun dun pe nwọn ti da Igbimọ Idajọ ti awọn alade *Judicial Council* silẹ ati "Kotu ẹ-tun y' ẹjọ mi wò' *Appeal Court*.

Ṣugbọn o sọ wipe nwọn ko ṣe dādā gẹgẹbi wọn iba ti ṣe nipa ti Kotu yi. O si gba wọn niyanju pupọ nipa rẹ.

### IṢẸ ỌNA TITUN.

O sọ fun wọn pe awọn Ijọba yio mā ṣe Ọna Ado lọ si Ọtûn lọ ati pe awọn Ijọba ti Ekiti ko ni dawọ iranlọwọ wọn duro nipa ti awọn ọna ti o jẹ ẹka ti o fi ori sọ ọna nla. O si tun sọ wipe awọn ọba nfẹ bi i pe i.i a fi owo ti nwọn fi nṣe ọna yi kun owo oṣu ti nwọn nsan fun wọn, awọn na si dahun nibẹ pe bẹni, o si wa la a ye wọn pe ko ti i le ri bẹ titi awọn ọna gbogbo yio fi pari.

### IROHIN EKITI FUN ỌDUN TI O KỌJA.

Ọlọla Lieut. Governor sọ fun awọn Ọba ti o pejọ pe inu oun dun pupọ fun iru irohin Ekiti ti oun ti ri gba ninu ọdun ti o kọja pe alafia wà lārin awọn Ọba ati awọn Ajẹlẹ ati pe ko si rúdurúdu kan. Ṣugbọn o jẹ nkan itiju lati gbọ pe awọn ara ilu kan pa

ẹnikan. Bikobaṣe ti apania yi, irohin na iba dara jalẹ, O si wa gba wọn niyanju pe ki nwọn ma tun jẹ ki oun mã gbọ iru irohin ipania bayi mọ

Lẹhin eyi, o sọ fun awọn Ọba pe oun ti pari ọrọ ti oun fẹ sọ wayi o, bi ẹnikẹni ba ni ọrọ lati sọ oun fẹ gbọ:

Ẹlẹkọle:-"A ki ọ, o ku abọ. Nipa ọrọ ilẹ mi ti o wa ni Omuo ti mo sọ pe mo fẹ gba pada nkọ?

Lieut-Gov."Mo ranti nipa rẹ. Njẹ mo rope o ti sọ fun awọn Ajẹlẹ nipa rẹ pẹlu?

Ẹlẹkọle: "Bẹni, mo ti sọ fun wọn."

Lieut-Gov:-"Mo ti wadi, mo si ti ri irohin lati ọdọ awọn Ajẹlẹ nipa rẹ, mo si wa ri i pe ki iṣe gbogbo awọn ara Ilu na lo fẹ pada wa si abẹ rẹ, nitorina kuku fi wọn silẹ.

Ẹlẹkọle:-"Bẹni, ọkunrin kan ti o wa nibẹ ti o njẹ Sunmọnu Tapà lo nru ọran na.

Lieut-Gov:-"O di igbati a ba ri i pe gbogbo wọn lo fẹ pada wa si abẹ rẹ ki a to le ran ọ lọwọ.

Ọdọfin Ado- "Oluwa mi Ewi ni Ado ki ọ pupọ o sọ wipe ãnu ṣe oun pe oun ko le wa nitori o ṣe oun bi ãrẹ."

Lieut Gov,-"O dara ba mi ki i pupọ ti o ba de ile."

Deji- "Mo fẹ sọrọ nipa ti Ọlọwọ Ọba Ọwọ.

Lieut Gov- "Gbogbo nyin fẹ papọ sọrọ nipa rẹ ni?

Deji "Bẹni, Ẹlẹkọle, jiṣẹ wa fun Gomina."

Ẹlẹkọle- " A sọ fun wa pe ọkan ninu wa, Ọlọwọ ọba Ọwọ, pe nwọn mu u, nwọn si fẹ ba a wi, ṣugbọn a ko mọ iru ẹṣẹ ti o ṣẹ, a fẹ mọ lati ọdọ rẹ, lẹhinna a si fẹ ṣipẹ rẹ, ki ẹ jọwọ ki ẹ da a fun wa.

Lieut Gov- "O ye mi nisisiyi pe, gbogbo nyin nfẹ bẹbẹ fun u. Ṣugbọn anu ṣe mi pe Ọlọwọ Ọba Ọwọ ko ka imọran Ajẹlẹ kankan si, ti nwọn ti mba a da nitori ko ma bã bọ sinu iyọnu ati pãpa nko ti imọ inkan ti mo le ṣe nisisiyi, nitori o di ọtunla ni ọjọ Jimọ ki ng to lọ si Ọwọ, ngo si lọ wadi gbogbo ọran wọnyi, nitoripe nitori bẹ ni mo ṣe wa lati Eko, lẹhin ti mo ba si ti wadi gbogbo rẹ tan ni ngo to mọ inkan ti mo le ṣe Ọrọ nyin tun ku bi?

Deji- " Bi mo ba tun ni ọrọ ngo ma ba *Resident* sọ."

Alãye- "Ẹ jọwọ ẹ ma gbagbe nipa ọna ti mo nfẹ ni Ilu mi ti yio lọ jade si ọna Ẹrinmọ

Lieut- Gov. "Lõtọ ọna Ilu rẹ ya si Ado pupọ ṣugbọn Oke pọ pupọ nibẹ.

Alaye- "Mo ti wa ọna ti ko ni ṣoro

Lieut Gov. "Bẹni mo mọ pe ni ọdun ti o kọja oyinbo *Engineer* olojuọna kan wa la ọna kan, ṣugbọn ọna na si wa Jinnà ju eyiti a ti ro lọ mo mọ dajn pe ti a ba ri ọna yi yio lere fun ara Ilu rẹ ati ara Ará lati ma fi ko ọja wọn lọ si Ileṣa ati Ọṣogbo yio si wa ri gẹgẹbi ọna Ilawẹ ti o fi ori sọ ti Igbara-odo

Alãye- "Mo ti ba Alara sọ ọ a si ti damọran nipa rẹ.

Lieut Gov.-"O dara bi o ba di ọdun ti mbọ a o wo eyi ti a o ṣe nipa rẹ.' '

Olojido- "Mo dupẹ lọwọ Gomina fun ọna Ilu mi ti nwọn nṣe, ṣugbọn o ku omi.

Lieut Gov- "Omi?"

Olojido- "Bẹni, omi ni. awọn oju odo ni mo nwi, lati fi afara dãdã si.

Lieut. Gov - Hẹnhẹn! mo ṣebi omi mimu lo nwi (Gbogbo enia rẹrin) o dara, awọn ti o ti ṣe oju ọna yio mura, nwọn o si ṣe awọn afara oju odo.

Ogoga- "Mo dupẹ fun ọna ti o ti de Ilu mi mo si fi inudidun ki ọ kabọ.

Lieut Gov.- "O dara, tal'o tun fẹ ba m ṣọrọ? Iba ṣe ninu awọn ti o joko si ẹhin tabi ti o wa woran ṣa? (ko si ẹnikan ti o dahun)

Lieut Gov- "Mo dupẹ lọwọ yin fun wiwa ti ẹ wa ri mi. Inu mi si dun pe ẹ gbadun irin ajo nyin nipa Mọto: Eyi mu iyatọ nlanlà wa si akoko ọdun marun sẹhin, ti ẹnyin pãpa ba si tubọ ṣe iranlọwọ si i, ẹ o ri pe iṣẹ na yio lọ siwaju, yio si jẹ anfani gbogbo nyin.

Mo nlọ sile nisisiyi nitori iṣẹ pupọ wa fun mi ni arọ yi lati ṣe. Bẹni ipade na si tuka

---

## Kaduna News.

### EMPIRE DAY & SCHOOL CHILDREN.

Since we returned from the Parade Field on the 24th May last, and nothing was done to cheer the School Children by way of feasting at Government expense, we hear the following expressions made by certain women public:

> "Ṣe bi Ọjọ Asè awọn Ọmọ Ile-iwe ni Empire Day? A ko ri iru ti Kaduna yi ri." (Is the Empire Day not a feasting day for School Children? We have never seen Schools like at Kaduna before).

Our feelings are pricked when we read of feastings of various Schools in various towns in the South. The following ex-